Bibeli fun awon omode



# Ijo pade Iyonu

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Aadota ojo leyin ti jesu Omo Olorun ji dide ninu oku, Emi mimo wa o si n gbe pelu awon omo eyin.  Bi o tile je pe ko ye awon omo eyin bawo ni Olorun Baba, Olorun omo (Jesu) ati Olorun Emi mimo se je Olorun kan, inu won dun pe Olorun wa pelu won.  Olorun se iyanu lati ran awon aposteli lowo lati so fun awon elomiran nipa Jesu.



Awon eniyan ti won gbagbo ninu Jesu pin ohun gbogbo ti won ni fun awon alaini ki won bale ba aini won pade.  Sugbon toko-tiyawo kan ti oruko won nje Anania ati Safira je alaisooto.  Won ta ile ti won ni, won si dipon bi eni pe gbogbo owo yii ni won gbe wa siwaju awon aposteli. Ni idakonko, won fi owo die pamo fun ra won.



"Kin lode ti Satani fi kun okan yin lati seke si Emi mimo...?"

Peteru beere lowo Anania "Iwo ko seke si eniyan bikose Olorun." Nigba naa ni Anania subu lule o si mi imi ikehin. Awon odomokunrin dii, nwon sigbe e jade, won sin in.



Ko pe leyin igba naa, Safira wole, laimo pe oko re ti ku. Oun naa paro lori owo naa – ohun ti o sele si oko re sele si oun naa. Eru nla si ba gbogbo awon ti o gbo oro yii.



Emi mimo nse ise ami ati ise iyanu laarin awon aposteli. Fun apeere, awon alaisan ri imularada nigbati Ojiji Peteru fe lu won.



O je akoko ise iyanu nla, lati fi iwalaaye Olorun han. Opolopo eniyan si gbagbo ninu Jesu. Eyi mu ki inu bi awon olori alufa gidigidi. Won si fi awon aposteli

sinu tubu.





Sugbon ni oru angeli Oluwa si ilekun ile tubu, o si mu won jade, o wi pe, “lo, duro ninu tempili ki o si maa soro iye yii.” Awon aposteli jade won si bere si ni waasu nipa Jesu. Ni owuro, awon olori alufa ba ile tubu ni sisofo.

Nigba ti o pada ri won, Olori alufaa, si bu awon aposteli. “Nje awa ko ti so fun o nikoko pe ki e mase koni' ni oruko yii mo?” “Awa ki yoo ha gbo ti Olorun ju ti eniyan lo,” Peteru ati awon aposteli dahun, Awon olori alufaa binu naa gidigidi. o si fe e pa awon aposteli. Dipo be, o pase pe kiwon nawon ki won situ won sile. Pelu inira yii, awon aposteli gboran si Olorun won si n tesiwaju lati maa waasu nipa Jesu.



Ni ojo kan, Okunrin kan ti a n pe ni Stefanu, won mu. Stefanu feran Jesu oluwa. Emi mimo n loo lati fun elomiran nipa Jesu. Awon kan paro, wi pe Stefanu soro tako Olorun. Leyin igbiyanju won, won so Stefanu li okuta pa nitori igbagbo re ninu Jesu.



Ki o tooku, Stefanu, kun fun emi mimo, O gbe oju soke orun o si ri Ogo Olorun ati Jesu duro ni owo otun Olorun. Opo eniyan soo lokuta, bi o ti n ke pe Olorun, "Jesu Oluwa, gba emi mi." Nigba naa, gege bi Jesu lori igi agbelebu, Okunrin onigboya yi, bi emi re ti bo lo, o si ngbadura ki Olorun ko darijin awon asekupani ree.



Iku Stefanu mu ki awon Inunibini kan tun dide. Odomodekunrin kan ti oruko re nje Soolu, ti o ti ran awon awon ti o pa sitifanu lowo, o mu awon Kristiani ti o bari, opolopo won sa lo kuro ni ile won, won si funka si ekun Judia ati Samaria.  Awon aposteli ni kan ni o duro si Jerusalemu.



Bi o tile je pe awon ota won wa ona lati pa won, awon to fonka lo si ibi gbogbo lati waasu ihinrere ayo nipa Jesu. Ko si ohun ti o ye kodi Olutele Jesu lowo – nitori Olorun Emi mimo n gbe inu won o si n sise pelu won.



Ijo pade Iyonu

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ise Awon Aposteli ori karun un de ikeje

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.